# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ỌRẸ AJYE TẸNI GBOGBO LAWA

No. 758 FRIDAY JULY 31, 1964 (2D)

## Olumofin Sọ Fun Benson Ki O Kuro Ninu Egbẹ N. C' N, C,

IBADAN:- Alakoso eto ẹkọ ni ipinle Iwọ Orun Naijiria ọgbẹni Daniel Olumofin sọ ni Ibadan ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kokandilọgbọn fun igbakeji ẹgbẹ Alakukọ ati Alakoso eto irohin fun Apapọ Ijọba Naijiria Oloye T. O. S, Benson pe ki o kuro ninu ẹgbẹ Alakukọ nisisiyi Ọgbẹni Daniel Olumofin sọ ninu ọrọ rẹ pe ohun mẹrin to mu on sọ pe ki Oloye Benson kuro ninu ẹgbẹ Alakuko ni pe Gbogbo iṣe ati akitiyan Oloye Benson ninu ẹgbẹ Alakukọ pe awọn ẹgbẹ na ko ka si nkankan rara.

Ọgbẹni Olunwofin tun so pe dipo ki awọn ẹgbẹ Alakukọ ma yin Oloye Benson pe nṣe ni awọn ẹgbẹ na kọ oju ija si ati pe bi nwọn yio sẹ le yo Oloye Benson kuro ninu ẹgbẹ na ni awọn ẹgbẹ Alakukọ nṣe bayi

Ọgbẹni Olumofin tun sọ pe dipo ki awọn ọmọ ẹgbẹ na ma yin Oloye Benson nṣe ni awọn olori ẹgbẹ Alakukọ kan ngbero gẹgẹbi nwon yio sẹ fi ẹhin rẹ jin le tabi ki nwọn gio lẹsẹ ni awọn enia nsẹ ti nwọn tun sọ pe nwọn ko ni igbẹkẹle lori Oloye Benson

Ọgbeni Olumofin so ni ikehin pe nṣe ni awon ẹgbẹ Alakuko nṣe Oloye Benson bi eniti enia ko fẹ tabi ọmọ ti awọn ọbi rẹ kọ silẹ.

Chike Obi Sọ Pe:

# OLOYE AWOLỌWỌ NI YIO DI IGBAKEJI AZIKIWE

## Ajumọṣepọ Egbẹ Dynamic Ati Afẹnifẹre Bajẹ

IBADAN:— Olori ẹgbẹ Dynamic Party ati ọjọgbọn kan ninu iṣiro ni ile ẹkọ giga julọ ti Unifasiti Ibadan tẹlẹ, Dokita Chike Obi sọ fun awọn oniwe irohin nigbati o de si ilu Ibadan ni irọlẹ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu [illegible] u nọsepọ ẹgbẹ on (Dynamic Party) ati ẹgb, Afẹnifẹre ti tu patapata.

Ninu ọrọ ti Dokita Chike Obi fi nye awọn oniwe Irohin ni ilu Ibadan lẹsẹkẹsẹ ti o de lati Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ni Dokita Obi sọ pe o ti han gbangba pe adehun si ti wa larin ẹgbẹ Afẹnifẹre pẹlu ẹgbẹ Alakukọ N. C, N. C. lori eto ajumọsepọ wọn eyiti ẹgbẹ Ọlọpẹ kuna lati jẹ ki on gbọ nipa rẹ rara.

Dokita Obi tun fi ye awọn oniwe Irohin siwaju si i pe awọn ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ṣe eto tan patapata pe ti nwọn ba le bori ninu idibo si ile Igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ti ilẹ Naijiria pe Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe ni yio tun wa gẹgẹbi Arẹ ilẹ Naijiria ti olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ yio wa gẹgẹbi Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria.



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

Dokita Obi tun sọ ninu ọrọ rẹ pe idi ohun to fa ti ẹgbẹ Afẹnifẹre fi kuna lati pe alajumọsepọ wọn (Dynamic Party) lati le fi ye wọn nipa eto adehun ajumọsepọ ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre ni yẹn

Dokita Obi tun fi ye awọn oniwe Irohin pe gẹgẹbi ẹgbẹ on ti fi otitọ ati ọkan funfun ba ẹgbẹ Afẹnifẹre lo pọ pe awọn ko tun le mọ pe ẹgbẹ Afẹnifẹre le tun ba ẹgbẹ Alakukọ ti o jẹ ọta gidigidi si ẹgbẹ mejeji ati pe toto ni ẹgbẹ on ti ṣe ileri pe ko si ẹgbẹ kankan ti awọn yio ba ṣe pọ rara mọ.

Dokita Chike Obi tun sọ pe ko si ẹgbẹ kankan ti ẹgbẹ on ba ni ajumọsepọ tẹlẹ laijẹ pe egbẹ Afẹnifẹre Dokita Obi sọ pe bayi awọn ẹgbẹ na si ti lodi ṣi adehun ti nwọn ba ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ati pe ko si eto ajumọsepọ kankan ti nwọn yio tun ba ẹgbẹ kan kan ṣe mọ

Ni ipari ọrọ Dokita Obi oni ti ẹgbẹ Afẹnifẹre ba le da wọn ati pe fun iduro sin sin ti awọn duro lẹhin ẹgbẹ Afẹnifẹre laseko ti ẹgbẹ na wa ninu wahala ati pe ohun to mu ẹgbẹ on ti nwọn ko ba ẹgbẹ kankan ṣe pọ lo mu ẹgbẹ Afẹnifẹre ki nwọn tu ajumọsepọ wọn pẹlu ẹgbẹ Alakukọ.

Oniwe irohin fi ye wa pe Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre



Dokita Nnamdi Azikiwe

Alhaji D. S. Adegbenro ko si ni ile nigbati Dokita Chike Obi nba awọn oniwe irohin sọ ni ilu Ibadan ati pe akọwe eto irohin fun ẹgbẹ Afẹnifẹre Ọgbẹni Bọla Ige to yẹ ki o tun fun awọn oniwe irohin ni ọrọ ni ọjọ na ko si ni ile o ti lọ fun ipade kan ni Argentina.

Nigbati awọn oniwe irohin tun lọ ba Alakoso eto ofin fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre fun ẹkun Ibadan Alhaji Busari Obisẹsan lati le sọ si gbogbo ọrọ ti Dokita Obi sọ Alhaji Busari Obisẹsan si da awọ oniwe Irohin pẹlu iwa itẹriba pe;

Alhaji Dauda Soroye Adegbonro ti o jẹ Adele olori ẹgbẹ Afẹnifẹre to yẹ ki o le fun awọn oniwe Irohin ni esi gbogbo ọrọ ti Dokita Chike Obi sọ lori ajumọṣepọ ẹgbẹ Afẹnifẹre

WO OJU EWE KẸFA



Dr Chike Obi

# IWE SI OLOTU

## Ki Irohin Imọlẹ Ma a Gberu si

Ni gbogbo igba ti a ba mbẹ ni aiye, ẹ jẹ ki o ma a bẹ Ọlorun jẹ ki o ran wa l o w ọ lati fun wa ni iye ati agbara lati le ma a gbinyanju ṣe iṣẹ ire, Ọlẹ ko wa si aiye ire, Ọlẹ tipatipa Ọlẹ dọyindọyin Ọlẹ alupa ma yiṣẹ ko ni kenke da,

'Iṣ eṣu ni ki Ọmọ enia ya ole Ọlẹ a ma a purọ kaakiri adugbo ni lati le ri okele bu, olẹ ni o ma a nva ṣolẹgiran tabi janduku enia Ọlẹ ni o edi o oyibiti tabi alagbeda Ọlẹ ni o ma a nsaba hu iwa aboosi ati iwa kẹnẹ ma ni

Ẹ jẹ ki a yin Ọlọrun logo ti ko gba eṣu laye lo si ṣe iwe Irohin Imọlẹ, ti eṣu ko si fi awọn alakoso ati olotu ati awọn Oṣiṣẹ iṣẹ iwe na gbe ṣe. Ti gbogbo wọn si le fi ifẹ gidi sowọpọ ti nwọn si nte apa mọ iṣẹ wọn lati Ọdun kan ti o pe loni. Eyi ti ko pe rara ti o si dabi ana Sowọpọ-ṣiṣẹ na si yori si ire iṣẹ iwe irohin ki iṣẹ kekere rara iṣẹ nla ni o jẹ o si jẹ ọkan ninu awọn iṣẹ ti o ṣoro tabi ti o nira pupọ lati ṣe Ẹni ti o ba gbe e wo ni yio mọ pe on wuwo.

Mo ki ẹnyin alakoso iṣẹ iwe Irohin Imọlẹ ati Olotu rẹ akowe kọkisa ati gbogbo ẹ yin Oṣiṣẹ iwe na lati oke dele laida ẹnikan si mọ si yin yin pupọ Mo kansansara si nyin gidigidi ẹ ku afọriti ẹ ku iṣẹ o Idi pataki ti mo fi kansara si nyin ni pe, ẹ nṣe iṣẹ na pẹlu gbogbo agbara nyin ati ifẹ ododo ati ti to ri pe, ẹ mọ pe iṣẹ ni oogun iṣẹ e si gbe iṣẹ na de aye kosemani lowurowuro Iwe Irohin Imolẹ ti di kosemani Ggbogbo enia ni nwon si fẹ lati ma a ra a ka lojoojumo ki Oluwa tubo ran Irohin Imolẹ lọwọ o, ki o si ma a gberu si.

Emi ni
Alhadji Y. A. Disu
Eko

## Irohin Imọlẹ Ijegede

Mo ki Olotu ati awọn alabaṣiṣẹ pọ rẹ fun iṣẹ ribiribi ti nwọn ṣe fun ilọsiwaju iwe Irohin Imọlẹ ati paapa julọ fun aikuna ti iwe Irohin imọlẹ ṣe lati igba ti o di iwe irohin ti njade lojojumọ, Eleyi papa si jẹ ohun to yẹ ki inu awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ ti iwe Irohin imọlẹ dun si nitori pe awọn agba ilẹ Yoruba lo npa lowe pe "Bi Eegun wa ba jo dada ara yio si ya Oluwa rẹ"

Nitori eyi eleyi jẹ ohun ayọ fun gbogbo awọn oṣiṣẹ ile na lati ri pe iwe Irohin Imọlẹ ni iwe irohin akọkọ ede Yoruba to nj de lojojumọ ni ilẹ karọ o jire Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria,

Eleyi tun jẹ ohun to yẹ ki gbogbo awọn onkawe Irohin Imọlẹ le mọ lati igba ti nwọn ti nka Iwe na pe gedegbe ni iwe na duro ko si fara mọ ẹgbẹ ojelu kankan ni ilẹ Naijiria ati pe irohin to ba jẹ otitọ ati ohun ti awọn Onkawe irohin imọlẹ ba ri ni nwọn mọ eleyi jẹ ohun ọpẹ fun awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ na papa julọ awon to wa nibi eto Irohin ile iṣẹ iwe Irohin Imolẹ. L'ẹkan si mo ki Olotu ati Alakoso ile iṣẹ na. Adura mi ni pe waju ni iwe na yio si ma lọ.

Emi ni,

Bayo Tiamiyu
IJẸBU-MUSHIN

## Irohin Imọlẹ Goke Agba

Inu mi dun pupọ loni lati lo anfani ti mo ni yi lati fi ki awọn Alakoso Olotu, oṣiṣẹ akọwe ati gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ ku ewu ẹrire ti gbojumọ Iwe Irohin Imọlẹ na pe ọdun kan ti o di iwe ojojumọ lẹhin ti a ti nṣe jade ni ọsọsẹ fun ọdun meje,

Mo pẹlu awọn ọkẹ aimọye olufẹ Iwe na lati dupẹ lọwọ Allah ti o ṣọwa di oni lati ba iwe na yọ. A tun dupẹ lọwọ Olodumare ti ko jẹki iwe na lu ẹjọ ni gbogbo asiko yi. Ti ko tun fi arẹ buruku ṣe awọn Alakoso Iwe na. Ọpẹ ni fun Oluwa.

Loni ti iwe na yio tun bẹrẹ ọdun miran Oluwa jọwọ maṣe jẹki iwe na ri ẹjọ maṣe so iwe na di ẹtọ ẹhin, iwaju ni opa ẹtiti nresi Oluwa Ọba adẹda iwaju ni ko jẹki ebiti iwe na ma resi.

Si awọn onkawe iwe na jọwọ Ọga Ogo ma bo aṣiri awọn onkawe na ibi ti nwọn ti mu owo fi nra iwe na ma jẹ o tan nibẹ oko Ọba ko si ṣa gbogbo wa lẹsẹ. Oluwa yio ma ṣe Olusọ aguntan wa a a ko ni rin lojo ti ebi pa ona a ko ni woko ni ojọ ti oko yio danu.

Mo yọ fun yin o, mo yọ fun ara mi o

Emi ni
Latifu Babalọla
Akọwe Agba Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

## Iwe Irohin Imọlẹ Di Ọmọ Ọdun meje

Ni Owurọ ana ni irohin Imọlẹ di ọmọ Ọdun meje? Mo ba ola ati awọn osisẹ irohin imọlẹ yọ Adura mi ni wipe ki Oluwa jẹ ki ẹmi iwe na ko gun Ilọsiwaju iwe na ni a o ma ri o. Airoju ati airaye ko ni ba gbogbo ẹnyin osiṣẹ Irohin Imọlẹ. Okọ ọba ni sa yin lẹsẹ.

Laisi aniani gbogbo ẹnyin ti ẹnka Irohin Imọlẹ lati igba aiye rẹ ẹ o ti wipe ninu Iwe ti o njade lede Yoruba Irohin Imọlẹ jẹ ọkan pataki o ma nfun wa ni ẹkun rẹrẹ irohin, ninu eyi ti a ti kọ ọpọlọpọ ogbọn. Ti orisirisi itan alarinrin ni a o sọ ni tabi ti ọrọ i mu ni larayа lati ọdọ awọn Aiẹgborodagba, Otẹlẹmuyẹn, Olofofo, ati awọn ti Mr Shoyinka, Alhaji Disu ati bẹbẹ lọ. Ninu gbogbo Iwe Irohin ti o jẹ edeYoruba, Irohin Imolẹ ni kan lo njade lojojumo,

Ki nto pari ọrọ mi nko ni salai dupẹ lọwọ awọn onkawe Irohin Imọle, nitori wipe awọn ni ẹmi na Awọn ni o jẹ okunrinfafa fun ilọsiwaju rẹ. Adura mi si yin ni wipe owo ko ni wọn yin. Iwaju ni ẹyin na yio ma lọ.

Ẹ ku Ọdun Odigba,
Emi ni
R. A. Dunmoye
Alaga Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye


HELLO HELLO HELLO

OLUSHI SOCIALISTS

PRESENT

FIRST ANNIVERSARY DANCE

at Foresters Centen..ry Hall
27, Odunlami Street Lagos

ON FRIDAY, 21st AUGUST, 1964, AT 6 p. m. till dawn

MUSIC BY

New Time Enterprises
Bashy & His Young Stars Orchestra

Ladies and Gents, dont be told of what happen at Foresters on that 21st August 1964, how Bashy will give you many latest hits and how New Time will give you many hits of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo & Broadway Dance Band from Ghana. Bashy is asuring you to bring along your Termogene or Mentholatum to rub your body after clocing.

COME THERE IN TIME TO AVOID RUSHING

Bar Bar 1nexhaustible

Tickets 3s Flat

Tickets obtainable at 16½ Bamgbose Street, Lagos (Irohin Imole Office) and at 3, Olushi Street Lagos.



BI O BA NI

1we—Titẹ

FUN

Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

Iwe Igbeyawo

KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸ IWE

Modupẹ Printing Press
16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495
Telephone : 21985, Lagos

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA
Dan wa wo lẹẹkan ṣoṣo ko si ri iyatọ

## Ẹmi Aṣe Ọpọ Ọdun Laiye

Lati Ọwọ E. ADEKUNLE ADENIJI.

Mo ki gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ l'Ọmọde ẹgbẹ mi ati agbalagba pẹlu ẹ ṣe

Inu mi dun lọpọlọpọ fun anfani ti Baba mi fun mi l'aye lati sọrọ lọjọ oni sinu Iwe Irohin Imọlẹ, eyi k ọ ni akoko kọwe sinu Irohin Imọlẹ eyini akoko ti ngo ki yin, ṣiwaju eyi mo nba awọn ẹlẹgbẹ mi sọrọ ni ṣugbọn eyi jẹ ti ajọdun ọdun kẹje ti Baba mi ti da Iwe Irohin Imọle silẹ ni ilu Eko ati ajọdun ọdun kan ti o ti bẹrẹ si jade ni ojojumọ

Nigbati Baba mi da iwe Irohin Imọle silẹ ni ọdun 1957 mo di ọmọ ọdun mẹrin mo wa ni Lady-Laki Nursry School YABA Sungbọn loni mo ni ayọ pupọ pe loni ti Baba mi nseajọdun ọdun kẹje ti oti da iwe Irohin Imọle silẹ mo di ọmọ ọdun mọk nla ati osu mẹta.

Nitorina pẹlu ayọ ati inu didun ni mo fi dupẹ lọwọ gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ pe Imọlẹ yio ko ni di okunkun lailai ẹ ko si ni se ti o.

# UROLYSAN DRAGES'

Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ (Kidney-Bladder) fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ ẹnu. ẹhin didun Ibadi Gige tabi riro, eri ile itọ, tabi lọ-jijo eniaitọ ritun, rukuruku. Pipọn, aikoleri itọ lati tọ to, lakuregbe, orunkun ọwọ, ẹsẹ, Ejika wiwu tabi riro Ara sisan. titobiju aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia didaj loru nigbakugba, ati orişirişi awọn aisan tabi amodi, ba wọn yi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti aiafia yio si de si ọ. Mej rẹko si ni ilu Naijiria nitorina ṣọra ki awọn eleru tabi awọn ori rọbirọbi ma ta orişi oni ran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba rara! Owo rẹ jẹ Sile mẹfa abọ 6/od owo Ọkọ Sila kan abọ (1/6d)



Bere Egbogi yi ni ṣọbu awọn:-
NIGERIA MEDICINE STORES
4ª TIUNBU SQUARE, LAGOS

# Ye Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan 21 - Feb 19) Nṣe ni ki o mura lati doju ija ohunkohun ti o ba de iwọ yio si ri iranlọwọ gidigidi nipa ọrọ na ṣugbọn bi o tiwu ki ara rẹ gbona t o nṣe ni ki oṣe suru ko si lọwọ.

PISCES (Feb 20 Mar 20) Ọjọ rere ni ọjọ oni jẹ fun nitoripe iwọ ni gbogbo enia yio gbẹkẹle ti nwọn osi ma reti ,ire kan yi tilẹ yọ siọ odara fun ọ lati kọwe si idalẹ tabi ki o rin irinajo

ATRIES (Mar 21 – April 19) Wa ọna ti gbogbo idi owọ yio kuro lọna, ni igbẹhin iwọ yio dopin iṣẹ rẹ, iṣẹ la yio si ṣe ni anfani.

TAURUS (April 20-May) Ọpọlọpọ yio ri pe ọjọ ẹbẹ adura ni oni yijẹ, nitori pe gbogbo ohun eto ti o nṣe ko ni nilari, iwọ yio si ma ri owo yanturu sugbọn ọra ni gbati o ba nwa mọto.

GEMINI (May 21-June 21) Orire ni tirẹ ori gbogbo ọjọ oni, sugbọn maṣe jẹki ọrọ ti ko to ọrọ ba ti rẹ jẹ ija kekere kan yio hẹ silẹ larin iwọ pẹlu ọrẹ re ẹkan.

CANCER (June 22-July 22 Ire mbẹ fun ọ nipokipo ti o ba wa wa loni, iwọ yio ri ifa owo jabirata kan jẹ, iwọ yio si tun ri irohin ayọ kan gba nile pẹlu.

LEO (July 23-August 23) Alafia yio de si ọ ara rẹ yio sile, dajudaj iwọ yio si dori awọn iṣoro gbogbo, ọjọ adura ẹbẹ fẹrẹ de na, o tọ ki o gbẹkẹle ara rẹ ki o si gbẹkẹle awọn ti o mbẹ nitosi rẹ.

VIRGO (Aug 24 – Sept 23) Ọjọ re ni oni jẹ fun ọ, gbogbo eto ti o wa ni idirẹ ti o ti yanju kedere ki o to de sakani ọdọ rẹ.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Iṣoro yio wa fun ọ, pẹlu idaduro, ti yio jẹki o ṣe amodi ati ọjọjọ gbindanwo, ki o si ṣe jẹjẹ ninu ile rẹ, fi ọgbọn ori rẹ ba awọn ọrẹ rẹ lo.

SCORPIO (Oct 24 - Nov) Gboke gbodo yio wa fun ọ loni, nigbẹhin rẹ iwọ ni yio ṣegun tẹle ọrẹ rẹ kan lesode. ibẹ ni iwọ yio ba ọrẹ titun miran pade

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Ipo ti o wa ti bẹ rẹ si yipada si rere, ohun ti o tọ ki o ṣe ni pe, ki o lo aseko eere na lati ṣe eto iṣẹ ti o wa nile ire nla jaburata yio kan ọ lara, ṣugbọn pa ẹnu rẹ mọ maṣe ba ẹnikan sọrọ rẹ

CAPRICORN (Dec 22- Jan 20) Maṣe jẹ ki ọda owo aisan bo ọ, ẹnikan ti iwọ yio pade loju ọna, mbọ wa di ẹni pataki fun ọ nitoripe Ọgbẹni ori rẹ ti pe.

# Awọn Ọja Ajẹbidan

we ilana ifa Iyanrin titẹ Etutu ṣiṣe dinsan lati egbo ajẹbidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku woyu okọ lẹnu mọ oso ati ajẹ ko ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ni ohunkohun toba si dawọ rẹle ni yio ja si rere awọn baba awon ti o gbowo gba asọ lọwọ enia ko ni ri gba mọ Iye owo rẹ 20/-

Iwe egbogi ajẹbidan Agbabiẹtu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wa ninu iwe yi ko ṣe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe yi lọwọ ṣaṣa arun ni o ko ni le wo ko si ni ijaiya pe arun tabi mimu. osika le pa ọ Iye owo 25/- e larin Ẹyọ Ajẹ ti o ba nfin turari yi ba a ti ṣe ṣure rẹ Ajẹ ati abatẹnijẹ ko ni foju si ọ lara ohun gohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwọ ko mọ aita ọja agbana ko si ni wọ igba rẹ idabobo siwa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| Pa golo kan | 10/6d |
| Kekere | 2/6d |
| Iwe Gbedegbẹyọ Hausa | 3/ |
| Itumọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Eewo ilẹ Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afọṣẹ Işẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 3/6 |
| ati agbara Psalm egun lori awọn Ajẹ pẹlu Ara | 30/- |
| Tailos Measurement works | 2/- 6d |
| Iwe lori iyege Ikọṣẹ (Certificate of Appreticeship) | 5/- |
| ẹyọ kan | 12/- 6d mẹta |
| Iwe Adehun larin Onile ati mehaya *Tenants* (Agrement Form) | 10/- 6d meji |
| Iwe Aṣofofo Alejo (Visitors not Book) | 2/-6d |
| Iwe Alagbafọ (Laundry Book) | 5/-6d |
| Kadi ifisọrọ sinu redio lọfẹ | 2d |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan fun itaja ati Iṣẹgun Ajẹ | 16/- |

## APEJUWE ILE IṢẸ WA

Wọ Bọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere bi, ti o ba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ti ile itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja rira adirẹsi mi niyi:—

Akiyesi Pataki:- ale ri awọn iwe wọn yi ra ni garage Iddo, Mushin, Ikorodu road ati gbogbo ile itaja iwe Ti o ko ba ri i ra wa si ọdọ mi ngo ta fun.

**J. O. Shoyinka**

c/o Postal Agent,
1, Isiba Street
Itirẹ Via,

# Si gbogbo Ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ Jakejado Agbaiye

Mo ju ba gbogbo ẹnyin o kawe mi lọmọde ati lagbalagba, Lọkunrin ati Lobinrin pe iwaju ni gbogbo nyin yio ma lọ.



ỌGBẸNI E. A. TAIWO ADENIJI.
Alakoso Ile Iṣẹ Iwe Irohin Imọlẹ

Mo si tun juba awọn oniwe Irohin gbogbo awọn na ni Daily Times, Daily Express, West African Pilot, Daily Telegraph ati awọn miran ti nko daruko wọn sibin.

Mo ki wọn lọpọlọpọ ikọwe nyin ko ni bi ọmọ araiye ninu.

Nigbati mo wo iwaju ti mo wo ẹhin mo ri wipe Iwe Irohin lede Gẹẹsi pọ lọ jara ṣugbọn iwe Irohin lede ti wa kọju ẹyọ meji tabi mẹta lọ, ninu gbogbo rẹ ẹyọkan ti Oruko rẹ njẹ Irohin Yoruba to njade ni ọsọsẹ deede, mo ṣe ibere kilo fa ṣugbọn rinu gbogbo idahun ti mo ri ko si eyiti o di ohun rere kan mu. Ni mo wa bẹ Ọlọrun ki o fun mi ni Imọ bi emi yio ti ṣe le da Iwe Irohin ni ede Yoruba fun anfani awa Ọmọ karo o jire' Nipa ifẹ Ọlọrun a da Iwe Irohin Imọlẹ silẹ ni ọjọ kẹta oṣu keje Ọdun 1957 ṣugbọn nigbati a ṣiri ilọsiwaju ti o nmu wa fun awọn ti ko gbọ ede Gẹẹsi laiko ro wahala ati ayan ti o mu dani mo tun bẹ Ọlọrun ati Ijọba aparọ pe ki awọn fun wa ni agbara lati tẹsiwaju fun iwe Irohin wọn si gba bẹ fun ni nitorina ni a ṣe bẹ rẹ si gbe iwe yi jade lojojumọ lati ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu keje Ọdun ti o kọja eyiti o pe Odunkan gbako lẹ n ti Irohin Imọ'ẹ ti njade lojojumọ,

Nitori idi eyi mo dupẹ pupọ lọwọ gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ fun inawo ojojumọ. Mo si tun wa dupẹ lọwọ gbogbo awọn opitan ti nwọn nfi itan orisirisi da gbogbo awọn onkawe Irohin Imọlẹ lara ya Iwaju ni gbogbo nyin yio ma lọ o, ajọṣe wa ko ni bajẹ.

ALAYE

Inu mi yio dun lọpọlọpọ lati ṣe alaye diẹ lori ọrọ Iwe Irohin Imọlẹ ko fi igba kan ba ẹnikẹni da imọ pọ ri bakanna si ni a ko fi ara mọ ẹnikẹni yala o ṣe rere ni tabi buruku eyiti o jẹ ọrọ ti yio mu itẹsiwaju ba ori le ede wa ni iwe temi ntele, Irohin wa lati ọdọ mekunnu kiṣe ti ẹgbẹ oṣelu kankan rara nitorina aye wa ninu rẹ ẹnikẹni ibaṣe olow tabi Mekunnu ni ko ba ti ẹnikẹni ja aye wa fun nyin lati sọ ẹdun ọkan nyin, paapa ni asiko yi ti IDIBO nbọ sọ edun ọkan rẹ sita ninu Irohin Imọlẹ ma jẹki o gbe inu rẹ ra si. Tẹmi kẹni ni Irohin Imọlẹ.


# I. C. M. Tọniki (Tabilets)




Gbiyanju lati ma lo I. C M. TỌNIKI nigbagbogbo I· C. M. TỌNIKI o wa fun Ọkunrin, Obinrin ati Alaboyun pẹlu. I. C. M. Tọniki c dara fun aini ẹjẹ to lara, o nfun ni lagbara, o si ntun ẹjẹ ṣe daradara. Bere fun ẹyọ igo kan, tabi dosini, ẹdidi Apo (50 dozes) wa pẹlu. Iler. i gun ọrọ o Bere lọwọ Elẹ gi ynbo ti o wa ni adu e rẹ fun I C. M. TỌNIKI (100 Tablets.)

Tabi ki o wa si ọdọ:—

MOSỌBALAJE MEDICINE STORES,
37, Palmchurch Sreet, LAGOS

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIK.



ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo a a Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ gbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin g ogbo'

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala şişẹşẹti o kọ ie jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala şişẹ tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata anu rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'i do dada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu igooaba-dun ati alafi diro de ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos.
hone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

ATI NI AWỌN ṢỌBU
OLODUMARE DISPENSARY
IṢẸ IBADAN

# Si gbogbo Enyin Onkawe Irohin Imole Jakejado Agbaiye

Mo ju ba gbogbo enyin o kawe mi lomode ati lagbalagba, Lokunrin ati Lobinrin pe iwaju ni gbogbo nyin yio ma lo.



OGBENI E. A. TAIWO ADENIJI.
Alakoso Ile Ise Iwe Irohin Imole

Mo si tun juba awon oniwe Irohin gbogbo awon na ni Daily Times, Daily Express, West African Pilot, Daily Telegraph ati awon miran ti nko daruko won sihin.

Mo ki won lopolopo ikowe nyin ko ni bi omo araiye ninu.

Nigbati mo wo iwaju ti mo wo ehin mo ri wipe Iwe Irohin lede Geesi po lo jara sugbon iwe Irohin lede ti wa koju eyo meji tabi meta lo, ninu gbogbo r e eyokan ti Oruko re nje Irohin Yoruba to njade ni osose deede, mo se ibere kilo fa sugbon rinu gbogbo idahun ti mo ri ko si eyiti o di ohun rere kan mu. Ni mo wa be Ọ.o run ki o fun mi ni Imo bi emi yio ti se le da Iwe Irohin ni ede Yoruba fun anfani awa Omo karo o jire' Nipa ife Olorun a da Iwe Irohin Imole sile ni ojo keta osu keje Odun 1957 sugbon nigbati a siri ilosiwaju ti o nmu wa fun awon ti ko gbo ede Geesi laiko ro wahala ati ayan ti o mu dani mo tun be Olorun ati Ijoba aparo pe ki awon fun wa ni agbara lati tesiwaju fun iwe Irohin won si gba be fun ni nitorina ni a se be re si gbe iwe yi jade lojojumo lati ojo kokanlelogbon osu keje Odun ti o koja eyiti o pe Odunkan gbako ko ti Irohin Imo'e ti njade lojojumo,

Nitori idi eyi mo dupe pupo lowo gbogbo enyin onkawe Irohin Imole fun inawo ojojumo. Mo si tun wa dupe lowo gbogbo awon opitan ti nwon nfi itan orisirisi da gbogbo awon onkawe Irohin Imole lara ya Iwaju ni gbogbo nyin yio ma lo o, ajose wa ko ni baje.

ALAYE

Inu mi yio dun lopolopo lati se alaye die lori oro Iwe Irohin Imole ko fi igba kan ba enikeni da imo po ri bakanna si ni a ko fi ara mo enikeni yala o se rere ni tabi buruku eyiti o je oro ti yio mu itesiwaju ba ori le ede wa ni iwe temi ntele, Irohin wa lati odo mekunnu kise ti egbe oselu kankan rara nitorina aye wa ninu re enikeni ibase olow tabi Mekunnu ni ko ba ti enikeni ja aye wa fun nyin lati so edun okan nyin, paapa ni asiko yi ti IDIBO nbo so edun okan re sita ninu Irohin Imole ma jeki o gbe inu re ra si. Temi keni ni Irohin Imole.


# I. C. M. Toniki (Tabilets)



Gbiyanju lati ma lo I. C M. TONIKI nigbagbogbo I. C. M. TONIKI o wa fun Okunrin, Obinrin ati Alaboyun pelu. I. C. M. Toniki o dara fun aini eje to lara, o nfun ni lagbara, o si ntun eje se daradara. Bere fun eyo igo kan, tabi dosini, edidi Apo (50 dozes) wa pelu. Iler. i i gun oro o Bere lowo Ele[illegible] ynbo ti o wa ni adu e re fun I. C. M. TONIKI (100 Tablets.)

Tabi ki o wa si odo:—

MOSOBALAJE MEDICINE STORES,
37, Palmchurch Sreet, LAGOS



GBOGBO ARA ILU NKO ORIN IYIN ati AYO NIPA "DYNAMIREN" TONIK.



ALE-BI-ELE Egbogi Toniki Jamonu titun ti gbogbo a a Ilu Eko ati jakejado Naijiria mo daju fun Ako gbara ati Ajebidan ise Re lara Agbalagba Okunrin g ogbo'

Bi are ara ba nmu o, nigbakugba fun wahala lala sisese ti o ko ie jeun daradara, tabi ki o male sun dada okun losan tabi loru tabi awon isan ara re gbogbo ki se fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunle daradara won ise tabi wahala sise tabi fun awon ailera gbogbo nyin ti ojo ori re (age) ba ti koja Ogbon odun o si de adorin tabi jube lo. Mo dupe "DYNAMIREN' ni egbogi ti e nfe lati so ara di otun pata-pata anu re a si jolo, eran ara re ti o ti hunjo yio bi e s'i do dada. Ara re yio ma gbe kankan nigbakugba y'Are" n gbakugba yio salo pelu igooaba-dun ati alafi diro de o. Iyen daju. Bere Egbogi na ni Sobu: awon

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos.
hone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

ATI NI AWON SOBU ISE OLODUMARE DISPENSARY IBADAN

IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 758. FIRDAY. JULY 31. 1964 (2D)

## Ẹgbẹ Ọmọ Ekiti Sọ Pe Ki Akintọla Fi Ipo Rẹ Silẹ

IBADAN:- Awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ ti Ekiti parapọ ẹgbẹ Afẹnifẹre kesi apapọ Ijọba Ilẹ Naijiria pe ki o lo ofin pajawiri ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati gba ijọba ipinlẹ Iwọ Orun fun igba diẹ lati le jẹ ki olotu ipinlẹ na fi aye silẹ.

Awọn ẹgbẹ ọdọ na tun se alaye idi ti emu wọn sọ pe ki oloye SL Akintọla fi iPo rẹ sile ni p gbogbo rogbo iya to bẹ silẹ ni ipinlẹ na bayi ati pe ko sin ofin ati ijọba rere ni ipinlẹ Iwọ Oru Naijiria nisisiyi

Awọn ẹgba ọdọ Ekiti Parapọ tun sọ pe Ijọba ipinlẹ Iwọ orun ti kuna lati se iṣẹ wọn l'ọna to tọ ati eyi to ye lati le d'ẹkun awọn iwa ti awọn ehanna ẹgbẹ oṣelu kan nhu ri ipinlẹ na ati pe ọpọlọpọ ẹmi lo ti padanu ninu rogbodiyan to bẹ silẹ na ati pe awọn ohun ini awọn enia ti ko mọwọ ti ko mọ ẹsẹ lo si ṣe'gbe p tapata.

Awọn ọmọ ẹgbẹ ọd na sọ pe ohun to yẹ bayi ni pe ki Ọlọla Abubakar gba Ijọba ipinlẹ Iwọ orun Naijiria nigbati Oloye Ainkintọla to jẹ olotu ipinlẹ na ti kuna ti tun lo ọgbọn ori rẹ lati le jẹ ki eto ofin ati alafia wa ni ipinlẹ na ati pe nitori na ki Alakoso Ijọba apapọ o ida rẹ lata le gbe eto ofin pajawiri de ipinlẹ na nisisiyi.

# Sardauna Sọ Pe Ajumọsepọ Ẹgbẹ N.P.C. Ati N.C.N.C. Yio Tu Ka L'ọdun Yi

JOS:- Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria ati Olori ẹgbẹ Olomi (N. P. C.) Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello Sardauna ilu Sokoto sọ ninu ọrọ rẹ ni ilu Jos ni Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria pe ajumosepọ ẹgbẹ on (N P C) ati ẹgbẹ Alakukọ N C N C yio tu ka ninu ọdun yi, Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello sọ pe yala ẹgbẹ on bori tabi nwọn kọ bori idibo ti ile Igbimọ asofin apapọ Ijọba ilẹ Naijiria eyiti nwọn yio se idibo rẹ ninu ọdun yi pe ẹgbẹ on (N P C) ko ni ba ẹgbẹ Alakukọ ṣe pọ mọ

Alakoso ijọba ipinlẹ Ariwa Naijiria nsọ eyi nigbati o nba awọn enia ipinlẹ rẹ nsọrọ ni ede Hausa ni ile Alakoso ipinlẹ na ni Tunde Jos nigbati awọn enia na wa fi ere ibilẹ wọn wa se eyẹ fun Alhaji Ahmadu Bello eyiti gbogbo awọn enia na si njo ni u jo nla kan to nrọ ni ọjọ ti awọn enia na ṣi njo ninu ojo nla to nrọ ni ọjọ ti awọn enia na nfi ere na nda Alakoso Ipinlẹ na laraya

Ninu ọrọ ti Alhaji Ahmadu Bello tun sọ fun awọn enia ipinlẹ rẹ ni ọjọ na ni pe ki awọn enia ipinlẹ gbiyanju lati gbagbe gbogbo ede aiyede to ti wa larin awọn enia ipinlẹ na ati lati le ni isowọpọ lati le gbogun ti awọn ipinlẹ kan ti Ọlọla Ahmadu Bello pe ni Yanmirin (Ibo)

Alakoso Ipinlẹ Ariwa ile Naijiria Alhaji Ahmadu Bello tun fi ye awọn enia Ipinlẹ rẹ awọn Ibo ki iṣe enia kan ti enia ni lati ba ma ṣe ọrẹ ati pe tẹlẹtẹlẹ re awọn Ibo ki iṣe ọrẹ awọn enia Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria ati pe awọn pẹlu Ibo ko ni jẹ ọkan ṣoṣo rara. Alhaji Ahmadu Bello tun ṣe alaye fun awọn enia rẹ pẹlu owe to lọ bayi pe Agbepọ pẹlu awọn Ibo pe nkan to jẹ ewu patapata ni, Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello tun se alaye rẹ ni ede Hausa ki awọn enia rẹ le mọ ohun to sọ eyiti o sọ bayi pe "Zammanu da su Zaman mania da doya"

ẸBẸ

Alakoso Ipinlẹ Ariwa Naijiria Alhaji Ahmadu Bello tun fi ye awọn enia rẹ pe awọn Ibo lọ jẹ ẹnikan to ni isowọpọ papọ o ni ṣugbọn isowọpọ awọn Ibo



Alhaji Ahmadu Bello

si jẹ fun Ipinlẹ wọn nikan Alhaji Ahmadu Bello tun ṣe apejuwe awọn Ibo gẹgẹbi awọn enia to je ki iṣọkan ilẹ Naijiria ko tete ni ilọsiwaju rara.

Alhaji Ahmadu Bello tun bẹ awọn enia ipinlẹ Ariwa Naijirira lati tete gbagbe edeaiyede to wa larin awọn enia ipinlẹ na tẹlẹ lati le jẹ ki gbogbo enia ipinlẹ na le ni emi iṣọkan fun ipilẹ Ariwa Naijira.

Alhaji Ahmadu Bello tun rọ awọn enia ipinlẹ rẹ lati le wa ni irẹpọ ati lati le gbogun ti awọn Ibo eyiti Alhaji Ahmadu Bello sọ pe awọn ni ko jẹ iṣọkan fun ilẹ Naijiria ati lati le fi opin si iyara enisoni ilẹ Naijiria.

Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello tun ṣe alaye fun awọn enia ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria lati le ri pe ni asiko idibo si ile Igbimọ asofin ti apapọ Ijọba pe nwọn ko fun awọn enia Ipinlẹ Gusu l'aye lati le bori Ibo kankan ni Ipinlẹ Ariwa rara asiko idibo to nbọ yi

Lẹhin ti awọn enia ilu Jos to wa fi ere pinlẹ Ariwa da Ọlọla Ahmadu Bello laraya jo ijo na tan ni Alhaji Ahmadu Bello ta awọn enia l'ọrẹ ẹwa le ni igba poun owo eyiti o fun awọn enia na.

Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello si ba mọ'to ayọkẹlẹ fi ilu Jos silẹ ni irọlẹ ọjọ na lọ ilu Zaria ibẹ na ni yio gba de si ilu Kaduna nibi ijoko Alakoso na.



Dokita M. I. Okpara

## Awolọwọ Ni Yio Di Igbakeji Azikiwe

Lati Oju Ewe Kini

ati ẹgbẹ Dynamic Party ti o sọ pe o ti tu patapata ni ko si ni ile lati le ṣe alaye lori ọrọ Dọkita Chike Obi boya ẹgbẹ Afẹnifẹre yio si ba ẹgbẹ Dynamic Party ṣe pọ mọ tabi ajumọ ṣepọ ẹgbẹ mejeji na ti tu gẹgẹbi olori ẹgbẹ Dynamic Party Dọkita Obi sọ loni fun awọn oniwe Irohin.

Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 31/7/64.